


**Nípasẹ̀ Ààrẹ Thomas S. Monson**

# Njẹ́ A Ti Múrasílẹ̀ bí?

Ní agbègbè ibití mo gbé nígbàkan rí, tí mo sì ti ṣiṣẹ́ sìn, Ìjọ ṣe iṣẹ́ ọ̀sìn Adìyẹ kan, tí àwọn ọ̀ṣìṣẹ́ ibẹ́ jẹ́ ọ̀ṣìṣẹ́ olùfarasin láìgbowo láti àwọn ẹka agbègbè náà. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ó jẹ́ iṣẹ́ ṣíṣe pẹ̀lú agbára, pípèsè ẹgbẹgbẹ̀rún ẹyin tuntun sí ilé iṣura ti Bíṣọ́ọ̀pù àti ọgọgọ́ọ̀rún pọ́ùn Adìyẹ pípa. Ní àwọn ìgbà díẹ̀, síbẹ̀síbẹ̀, jíjẹ́ àwọn àgbẹ̀ olùfarasìn láìgbowó ti ìlú-nlá kò túmọ̀ sí ìléroro lórí ọwọ́ nikan ṣùgbọ́n ó jẹ́ ìbàjẹ́ ọkàn àti inú pẹ̀lú

Fún àpẹrẹ, Láéláé ni èmi yíò fi máa rántí àsìkò náà tí a kó àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin Oyè Àlùfáà Áárọ̀nì jọ láti mú kí ibi iṣẹ́ yí wà ní mímọ́ ní àsìkò rírú ewe. Àpéjọ wa tí ó ni akitiyan áti ọ̀pọ̀lọpọ̀ okun inú kórajọ ní ibi iṣẹ́ náà àti ní àrà kóyákóyá kan wọ́n fa àwọn ewéko àti ìdọ̀tí tu ní ìwọ̀n tó tóbi, wọ́n sì kó wọn jọ, wọ́n sì jó wọn. Nípa ìmọ́lẹ̀ ti iná ńlá tó ńtàn, a jẹ búrẹ́dì tó ní ẹran nínú, a sì bu ìyìn fúnra wa lórí iṣẹ́ náà tí a ti ṣe dáradára.

Síbẹ̀síbẹ̀, ìṣòro kan ṣoṣo tó ní jàmbá nínú ló wà. Ariwo àti iná náà dààmú iye àwọn ẹgbẹ̀rún márún abo Adìyẹ tó ńyé ẹyin gidi tí ó fi jẹ́ pé ọ̀pọ̀ lára wọn bẹ̀rẹ̀ sí nyọ ìyẹ́ fúnra wọn sílẹ̀ láìròtẹ́lẹ̀, wọ́n sì dáwọ́ ẹyin yíye dúró. Lẹ́hìn èyínáà a gba àwọn ewéko díẹ̀ láàyè kí a bàá lè mú ẹyin púpọ̀ jáde

Kò sí ọmọ Ìjọ tí ó ti ṣèrànwọ́ láti pèsè fún àwọn wọnnì tí ó ṣe àìní tí yíò gbàgbé tàbí kábámọ̀ ìrírí náà. Ilé Iṣẹ́, ìṣúná, ìgbẹ́kẹ̀lé ara ẹni, àti ṣíṣe àbápín pẹ̀lú àwọn míràn kò jẹ́ tuntun sí wa.

A níláti rántí pé ètò ilé iṣura tó dára jùlọ yíò jẹ́ fún gbogbo ìdílé nínú Ìjọ láti ní àfikún oúnjẹ, aṣọ, àti, níbi tó bá ṣeéṣe, awọn ohun àìgbọdọ̀ mání ti ìgbé ayé. Ilé ìṣura ti Olúwa ní nínú rẹ̀ àsìkò, àwọn ẹ̀bùn, àwọn iṣẹ́ afọgbọ́n ṣe, àànú, ohun èlò ìyàsímímọ́, àti ọ̀nà tí a ngbà ní owó ti àwọn olótítọ́ ọmọ Ìjọ. Àwọn ọnà ìrànlọ́wọ́ wọ̀nyí wà fún bíṣọ́ọ̀pù ní ríran àwọn tó ṣe aláìní lọ́wọ́.

A rọ gbogbo Àwọn Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́ Ìkẹhìn láti jẹ́ amòye ní ṣíṣètò wọn, láti jẹ́ oníwọ̀nba ní ìgbé ayé wọn, àti láti yẹra fún àṣejù tàbí gbẹ̀sè tí kò yẹ. Ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn púpọ̀ lè yí ìjì ìrú omi-síhín sọ́hún jáde kúrò nínú ìṣúnná ìgbésí ayé wọn tí wọ́n bá ni àfikún ti oúnjẹ àti aṣọ àti pé tí wọn kò bá jẹ gbèsè . Lóní a rí pé ọ̀pọ̀ ti tẹ̀lé ìmọ̀ràn yí ní ìpadàsẹ́hìn: wọ́n ní àfikún ti gbèsè wọ́n kò sì ní oúnjẹ.

Mo tún ohun tí Ìgbìmọ̀ Àrẹ Àkọ́kọ́ kéde ní ọdún díẹ̀ sẹ́hìn sọ:

"A ti gba Àwọn Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́ Ìkẹhìn nímọ̀ràn fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún láti múrasílẹ̀ fún ìpọ́njú nípa níní láti mú owó kékeré kan kalẹ̀ sẹ́gbẹ́. Ṣíṣe bẹ́ẹ̀ nṣe àfikún ní ọ̀nà àìníwọ̀n sí ààbò àti wíwà lálàfíà. Olúkúlukù ẹbí ní ojúṣe kan láti pèsè fún àwọn ohun àìní ara tirẹ̀ dé ibí tí ó bá ti ṣeéṣe.

"A gbà yín níyànjú níbikíbi tí ẹ lè máa gbé nínú ayé láti múrasílẹ̀ fún ìpọ́njú nípa wíwo ipò àwọn ìnáwó yín. A rọ̀ yín láti ṣe ìwọ̀ntúnwọ̀nsì ní nínáwó yín, ẹ kóra yín níjánu níti àwọn ọjà rírà yín láti yẹra fún gbèsè. Ẹ san gbèsè yín kúrò kíákíá bí ẹ ṣe lè sán, kí ẹ sì yọ ara yín kúrò nínú ìgbèkùn yìí. Ẹ tọ́jú owó kékeré kan déédé láti kọ́ ìṣúra ìnáwó pamọ́ díẹ̀díẹ̀."[1]

Njẹ́ a ti múrasílẹ̀ fún àwọn àìbámọ̀ nínú ìgbésí ayé wa bí? Njẹ́ àwọn iṣẹ́ àfọgbọ́n ṣe wa wà ní pípé bí? Njẹ́ à ńgbé ìgbé ayé ìpèsè sílẹ̀ fún ọlá bí? Njẹ́ a ní ìfikún ní ìpamọ́

lọ́wọ́ bí? Njẹ́ a gbọ́ran sí àwọn òfin ti Ọlọ́run bí? Njẹ́ à ńdáhùn sí àwọn ẹ̀kọ́ ti àwọn Wòlíì bí?. Njẹ́ à ti múràsílẹ̀ láti fún àwọn òtòṣì, àwọn aláìní lára ohun ìní wa bí? Njẹ́ a wà níbámú pẹ̀lú Olúwa bí?

À ńgbé ní àwọn ìgbà rúdurùdu. Nígbàpúpọ̀ a kìí mọ̀ ọjọ́ ọlà; nítorínáà, ó yẹ fún wa láti múra sílẹ̀ fún àwọn àìdánilójú àkókò. Nígbàtí àsìkò fún ìpinnu bá dé, àsìkò fún ìmúrasílẹ̀ ti kọjá.

**ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ́**

1. Ìgbìmọ̀ Ààrẹ àkọ́kọ́, *A Ti Kó Gbogbo Rẹ̀ Jọ Nípamọ́: Àwọn Ìnáwó Ẹbí* (pamphlet, 2007).

### ÌDÁNILẸ́KỌ̀ LÁTINÚ Ọ̀RỌ̀ YÌÍ

Gbígbèrò àwọn àìní i àwọn tí ẹ̀ ńbẹ̀wò, ro àwọn ọ̀nà tí ẹ lè fi ràn wọ́n lọ́wọ́ láti di alágbẹ́kẹ̀lé ara ẹni nínú ìgbàsíṣẹ́, àwọn ìnáwó, oúnjẹ fífipamọ́, tàbí ìmúrasílẹ̀ àìrótẹ́lẹ̀. Ro nípa iṣẹ́ afọgbọ́n ṣe kan tí ẹ lè ṣe àbápín pẹ̀lú wọn, irú bíi gbígbin èso nínú ọgbà tàbí àbójútó owó, tí yíò fún wọn lágbára láti tẹ̀lé ìmọ̀ràn ti Àrẹ Mónson.

## ỌDỌ́

## Mo Ṣiṣẹ́ Sìn Lẹ́ẹ̀kansi

**Nípasẹ̀ Jaíne Araújo**

Ní ọjọ́ kan, lẹ́hìn pípari ṣíṣe iṣẹ́ ìsìn kan, mò ńrìn kọjá ilé ìpàdé wa mo sì rí àwọn arábìnrin méjì tí wọ́n ńnu ilé náà. Àwọn ọ̀rọ̀ mi kàn jáde síta: "Ẹ̀yin Arábìnrin, njẹ́ ẹ nílò ìrànlọ́wọ́ díẹ̀ bí?" Ọ̀kan lára wọn rẹ́rín sí mi ó sì sọ pé mo ti dé ní àsìkò tó tọ́ nítorí àwọn nìkan ni wọ́n ńṣiṣẹ́ nínú ilé náà ó sì ti rẹ̀ wọ́n gidigidi. Ó sọ pé òun ti gbàdúrà pé Olúwa yíò rán ẹnìkan láti ṣèrànlọ́wọ́. Inú mi dùn gan an láti jẹ́ ìdáhùn sí àdúra rẹ̀. Mo ṣẹ̀ṣẹ̀ parí ṣíṣe íṣẹ́ ìsìn fún ẹlòmíràn ó sì ti rẹ̀mí pẹ̀lú, ṣùgbọ́n mo tẹ̀lé ọkàn mi mo sì jọ̀wọ́ arà mi láti ṣe iṣẹ́ ìsìn síi.

Òfin kan ni ó jẹ́ láti ṣiṣẹ́ pẹ̀lú ayọ̀ (wo D&C 24:7) Nígbàtí a bá nífẹ́ láti ṣiṣẹ́ sìn ní gbogbo ìgbà, a lè ṣe ìranlọ́wọ́ láti mú kí àwọn ìyanu ṣẹlẹ̀ nínú ayé àwọn ẹlòmíràn. Ìgbé ayé wa ńdi èyítí o nitumọ̀ si nígbàtí a bá ṣiṣẹ́ sìn. Nítòótọ́ Olúwa fẹ́ràn wa, Ó ńran ìkọ̀ọ̀kan àwọn ọmọ Rẹ̀ lọ́wọ́, Òun yíò sì fún wa ni agbára láti ṣiṣẹ́ sìn.

*Olùkọ̀wé náà ńgbé ní Rio Grande do Norte, Brazil.*

## ÀWỌN ỌMỌDÉ

## Njẹ́ Ẹ Ti Múrasílẹ̀ bí?

Àwọn Ìdáhùn: Òtítọ́, Òtítọ́, Iró, Òtítọ́, Iró

Ààrẹ Monson ti ní kí olúkúlukù wa múrasílẹ̀ fún àwọn àkókò ìnira àti láti ran àwọn ẹlòmíràn lọ́wọ́ nínú àwọn àkókò ìnira wọn. Ṣe ìdánwò ránpẹ́ yìí kí o sì mú òtítọ́ tàbí Iró gẹ́gẹ́bí ìdáhùn láti ríi bóyá o ti ṣe tán!

Mo lè fi ìgbàgbogbo rí ẹnìkan láti ràn lọ́wọ́.

Òtítọ́ ☐ Iró ☐

Mo lè fi ìmoore hàn fún gbogbo nkan tí mo ti ní.

Òtítọ́ ☐ Iró ☐

Èmi kò ní ẹ̀bùn kọkan láti ṣe àbápín pẹ̀lú ẹnìkan.

Òtítọ́ ☐ Iró ☐

Fífowó pamọ́ fún ẹ̀hìn ọlà jẹ́ iyè inú rere kan.

Òtítọ́ ☐ Iró ☐

Mo nílò àwọn ìṣeré tuntun àti àwọn aṣọ láti ní inúdídùn.

Òtítọ́ ☐ Iró ☐

© 2014 Nípasẹ̀ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀ẹ́ ní USA. Àsẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/14. Àṣẹ Ìtumọ̀: 6/14.
Ìtumọ̀ ti *First Presidency Message, September 2014*. Yoruba.10869 779

# Iṣẹ Ìránṣẹ́ tọ̀run ti Jésù Krístì: Olùtùnú

Ìgbàgbọ́, Ìdílé, Ìrànlọ́wọ́

*Ẹ fi tàdúrà tàdúrà ṣe àṣàrò ọ̀rọ̀ yìí kí ẹ sì ṣàwárí lati mọ̀ ohun tí ẹ ó ṣe àbápín. Báwo ni níní òye ìgbésí ayé ati ojúṣe Olùgbàlà yíò ṣe mú kí ìgbàgbọ́ yin nínú Rẹ̀ pọ̀ si, ti yíò sí bùkún awọn wọnnì tí ẹ̀yin ńbójútó nípasẹ̀ kíkọ́ni nípa bíbẹniwò?* ***Fún ìwífúnni síi, lọ sí reliefsociety.lds.org***

*Èyí jẹ́ apákan nínú onírurú àwọn Ọ̀rọ̀ Abeniwò Kíkọ́ni tí ó ńfi awọn ìwò ti iṣẹ́ ìrànṣẹ Olùgbàlà hàn.*

Jésù Krístì ṣèlérí pé, "Èmi kì yíò fi yín sílẹ̀ ní alâìní bàbá: èmi óò tọ̀ yín wá" (John 14:18). Òun yíò fún wa ní "ọ̀ṣọ́ fún eérú, òróró ayọ̀ fún ọ̀fọ̀" (Isaiah 61:3). Nítorí Krístì jìyà Ètùtù fún olúkúlukù wa, Òun kò ní gbàgbé wa. "Olùgbàlà wa ti gbe lé órí ara Rẹ̀ . . . àwọn ìrora wa àti ìjìya wa àti àwọn ìpọ́njú wa kí Òun lè mọ irú ìmọ̀lára tí à ńní àti bí Òun ṣe lè tù wá nínú," ni Linda S. Reeves sọ, olùdámọ̀ràn kejì nínú Ìgbìmọ̀ gbogbogbò Ẹgbẹ́ Ìrànlọ́wọ́.[1]

Mímọ̀ pé Krístì yíò tù wá nínú lè mú àláfíà bá wa, yíò sì fún wa ní ìmísí láti tẹ̀lé àpẹrẹ Rẹ̀ nípa ṣíṣe iṣẹ́ ìránṣẹ́ fún àwọn ẹlòmíràn. Àrẹ Thomas S. Monson sọ pé: "Òye wa nípa ìhìnrere àti ìfẹ́ wa ti Bàbá wa Ọ̀run àti ti Olùgbàlà wa yíò tù wá nínú, yíò sì mú wa dúró yíò sì mú ayọ̀ wá sí ọkàn wa bí a ṣe ńrìn ní ọ́nà tó tọ́ tí a sì ńpa àwọn òfin mọ́. Kì yíò sí ohunkóhùn nínú ayé yí tí ó lè ṣẹ́gun wa."[2]

### Láti inú Àwọn ìwé Mímọ́

John 14:18, 23; Alma 7:11–13; Ẹkọ́ áti àwọn Májẹ̀mú 101:14–16

### Láti inú Ìwé Ìtàn Wa

Elaine L. Jack, Àrẹ gbogbogbò ìkejìlá ti Ẹgbẹ́ Ìranlọ́wọ́, sọ pé: "Nípa Abeniwò kíkọ́ni à ńran ara wa lọ́wọ́. Ọwọ́ máa ńfi ìgbà púpọ̀ sọ̀ ohun tí ohùn kò lè sọ́. Ìdìmọ́ra pẹlú ìfẹ ńfi ìtumọ̀ púpọ̀ hàn. Rínrín ẹ̀rín papọ̀ ńmú wa ní ìrẹ́pọ̀. Àsìkò àbápín ńmú ọkàn wa sọjí. A kò lè fi ìgbàgbogbo gbé àjàgà tí ẹnìkan tó nídàmú kúrò, ṣùgbọ̀n a lè gbée sókè kí òun lè gbàá mọ́ra dáadáa."[3]

Àwọn arábìnrin Ẹgbẹ́ Ìranlọ́wọ́ tí wọn jẹ aṣaájú wa "rí agbára ti ẹ̀mí gbà nínú ìfẹ́ àti àánú ara wọn. . . . Gẹ́gẹ́bí wọ́n ṣe jìyà àwọn àdánwò àti àìsàn àti ikú, wọ́n gbàdúrà nínú ìgbàgbọ́ fún ara wọn, wọ́n sì tu ara wọn nínú. 'Ìfẹ́ ti Ọlọ́run ńṣàn láti inú ọkàn sí ọkàn,' Helen Mar Whitney kọwé pé, 'títí tí ẹni burúkú náà bá dàbí alâìlágbára nínú ìgbìyànjú rẹ̀ láti gba àárín wa àti Olúwa, àti ọ̀kọ̀ ìkà rẹ̀, ní àwọn àpẹrẹ, ni wọ́n gbọn oró wọn dànù.'"[4]


**ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ́**

1. Linda S. Reeves, "Olúwa kò Tí i Gbàgbé Rẹ," *Ensign* or *Liahona,* Nov. 2012, 120
2. Thomas S. Monson, "Ẹ Tújú Ka," *Ensign* or *Liahona,* May 2009, 92.
3. Elaine L. Jack, ní *Àwọn Ọmọbìrin ní Ìjọba Mi: Ìwé Ìtàn àti Iṣẹ́ Ẹgbẹ́ Ìranlọ́wọ́* (2011), 119.
4. *Àwọn Ọmọbìrin ní Ìjọba Mi,* 171.


### Gbèrò Èyí

Báwo ni níní òye pé Olúwa ńrántí yín ṣe ńmú ìtùnú wa fún yín?

© 2014 nípasẹ̀ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀ẹ́ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/14. Àṣẹ Ìtumọ̀: 6/14.
Ìtumọ̀ ti *Visiting Teaching Message, September 2014.* Yoruba.10869 779